# “Ẹni tí ó bá gba ìmọ̀ latara ìràwọ̀, onítọ̀hún ti gba ẹka kan ninu oògùn, bi o ba ṣe n lekun ninu imọ ìràwọ̀ naa ni kikọ oògùn rẹ naa ṣe maa lékún”

Lati ọdọ ọmọ Abbaas- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- o sọ pe: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ẹni tí ó bá gba ìmọ̀ latara ìràwọ̀, onítọ̀hún ti gba ẹka kan ninu oògùn, bi o ba ṣe n lekun ninu imọ ìràwọ̀ naa ni kikọ oògùn rẹ naa ṣe maa lékún”.

[O ni alaafia] [Abu Daud ati Ibnu Maajah ati Ahmad ni wọ́n gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe ẹni ti o ba kọ́ imọ ìràwọ̀, ati fifi lílọ-bíbọ̀ rẹ, ati ìwọlé rẹ, ati ìjáde rẹ ṣe itọka si awọn ìṣẹ̀lẹ̀ orí ilẹ̀, bii ikú lagbaja, tabi iṣẹmi rẹ, tàbí àìsàn rẹ, ati nǹkan ti o jọ ìyẹn ninu nnkan ti o maa ṣẹlẹ̀ ni ọjọ́ iwájú, onítọ̀hún ti kọ́ ẹ̀yà kan ninu oògùn, bi èèyàn ba ṣe n kọ́ ọ sí naa ni yoo ṣe maa pọ̀ ni oògùn sí.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5989